# IDANWÒ IGBAGBỌ́

**Jakọbu 1:1-21; 1 Peteru 1:1-9; 4:12-19.**

**ẸKỌ 448 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKOSORI: "Bi o ba jiya bi Kristiani, ki oju ki o máṣe ti i; ṣugbọn ki o kuku yin Ọlọrun logo ni orukọ yi" (1 Peteru 4:16).**

## Ohun ti a Kọ́

Ẹyin ọmọde mọ bi o ti ri lati yege ninu idanwo ni ile-ẹkọ nibi ti ẹ ti n kọ́ ede Oyinbo, iṣiro, ẹkọ nipa ibagbepọ laaarin ara wa, ati oriṣiriṣi nnkan miiran ti yoo ràn yin lọwọ nigba ti ẹ ba dagba lati le ṣiṣẹ oojọ yin, lati tọju ile, ati lati jẹ́ ọmọ ibilẹ rere ni ilu yin. Ninu ẹkọ Ile-Ẹkọ Ọjọ Isinmi ti oni a n kà nipa idanwo ni ile-ẹkọ ibi ti a ti n kọ́ lati fẹran Ọlọrun ati awọn ọrẹ ati aladugbo wa, ati lati di Onigbagbọ́ rere.

## Oriṣiriṣi Idanwo

Njẹ itọni ti a kọ́ fun ni ninu ẹkọ wa ni pe, "Nigbati ẹnyin ba bọ́ sinu onirũru idanwò, ẹ kà gbogbo rẹ̀ si ayọ". Ki ni "idanwò" ti yé ọ si? O le ro pe ohun ti o dùn mọ ni ti o si dabi ẹni pe o wu ni ṣugbọn ti o lodi tabi ti o lu mọ ẹ̀ṣẹ ni. Ni tootọ, eyi jẹ́ oriṣi idanwo kan. Oriṣi idanwo miiran wà lati yiiri, tabi lati dán igbagbọ́ Kristiani ninu Ọlọrun wò.

Nigba ti a kọ́ di ọmọlẹyin Jesu a ni igbagbọ́. A wá si ọdọ Ọlọrun a jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, a si bẹ Ẹ pe ki O gbà wá là. A ni igbagbọ́; a gbagbọ́ pe Ọlọrun gbọ́ adura wa, a si gbagbọ́ pe O gbà wá là ati pe Oun yoo pa wa mọ́ ninu igbala ni ọjọ ayé wa gbogbo. Lẹyin naa iyiiriwo tabi idanwo dé lati dán igbagbọ́ wa ninu Ọlọrun wò. Awa ha gbagbọ́ sibẹ pe Ọlọrun yoo pa wa mọ́ ninu oore-ọfẹ bi idanwo tilẹ gbona, bi o tilẹ ṣoro lati fara dà?

Nigba ti Jakọbu Aposteli kọ itọni yii pe, "Nigbati ẹnyin ba bọ́ sinu onirũru idanwo, ẹ kà gbogbo rẹ̀ si ayọ", ohun ti o n sọ ni pe, maa yọ̀ nigba ti oniruuru idanwo tabi iyiiriwo ba de si ọ. Ki ni ṣe? Nitori nigba ti iwọ ba fi ayọ̀ doju kọ idanwò ati iyiiriwo igbesi-ayé rẹ, gẹgẹ bi a ti ni ki o ṣe, iwọ yoo kọ́ suuru, eyi yoo si sọ ọ di Onigbagbọ́ rere.

Ni ọjọ ti o kọkọ ka ẹkọ kan lati inu iwe rẹ ni ile-ẹkọ, iwọ ha le dahun idanwò lori rẹ? Rara, o ka a lọpọlọpọ igba; o ṣe idaraya ninu rẹ̀ tabi arokọ lori ẹkọ naa. O fi ẹnu dahun ibeere miiran. O n ka a ni aka-tun-ka lojoojumọ, nigba naa ni o to le yege ninu idanwo naa. Bẹẹ naa ni ile-ẹkọ Ọlọrun -- o ko le kọ́ lati di Onigbagbọ́ alagbara ninu ẹkọ kan, nitori naa ki o má ṣe yà ọ́ lẹnu nigba ti iyiiriwo kan ba n tẹle ekeji ni ọ̀na rẹ.

## Fun ni Okun si i

Bi o ti n ka ẹkọ yii lonii, o ṣi jẹ́ ọtun ni àya rẹ; bi idanwo lile kan ba de si ọ, boya iwọ yoo le ranti lati fi ayọ̀ ati suuru gba a. Ṣugbọn ni ọsẹ ti n bọ̀ o le fẹ pẹlu awọn akọrin ile-ẹkọ rẹ, olukọ si le wi pe ko si aye fun ọ mọ́ nitori gbogbo àye akọrin ti o wà ni wọn ti di. Iwọ o ha faya rán iyiiriwo yii lai fi aye silẹ fun idanwo lati mu ọ barajẹ tabi lati ni ẹtanu si olukọ rẹ nitori kò yàn ọ́, tabi lati jowu awọn ti o ni anfaani ti iwọ paapaa n fẹ ni?

Iwọ yoo bori idanwo naa bi o ba ranti ẹkọ ti a kọ́ ọ, "Ẹ kà gbogbo rẹ̀ si ayọ"; si duro ṣinṣin lori igbagbọ́ ati igbẹkẹle ti o ni ninu Ọlọrun nigba ti a ṣẹṣẹ gbà ọ́ là. Bi iwọ ti n gbadura ti o si n sinmi le E lati la ọna silẹ fun ọ lati ni gbogbo anfaani ti Oun mọ pe yoo dara fun ọ, igbagbọ́ ati ifẹ rẹ si Ọlọrun yoo maa lokun si i. Eyi yoo sọ ọ di Onigbagbọ́ alagbara, ti o le fi suuru ati iduroṣinsin fi aya rán awọn idanwo miiran ti n bọ̀ ni ọjọ iwaju.

**Idanwo Miiran**

Boya ni ibẹrẹ ọdun iwọ ati ọrẹ rẹ fẹ́ fi orukọ silẹ lati kọ́ iwe titẹ̀. Olukọ fi orukọ ọrẹ rẹ silẹ ṣugbọn o kọ̀ lati gbà ọ́. Ijatilẹ ti o mu ọ lọkàn ni eyi jẹ́. Idanwo ti o le mu ọ binu niyii, ṣugbọn ko le to iyiiriwo ti akọkọ. Lẹṣẹkẹṣẹ iwọ yoo ranti bi Ọlọrun ti ràn ọ lọwọ ni igba akọkọ iwọ o si duro ṣinṣin lori ipinnu rẹ lati tun gbẹkẹle E ninu idanwo yii pẹlu.

Iwọ n dagba sinu pipe ti ẹkọ wa n sọ nipa rẹ̀: ipo ti iwọ o ni itẹlọrun, ti iwọ o ni agbara lati gbẹkẹle Ọlọrun ni igba aini gbogbo.

**Iranwọ Ọlọrun**

Idanwo ti o le ju bẹẹ lọ tun le de ba ọ. Njẹ bi a ba fi ẹsun sun ọ pe o ji apo owo ẹlẹgbẹ rẹ ni ile-ẹkọ? O ṣe e ṣe ki olukọ yin paapaa gbagbọ pe iwọ ni o ji i, nitori iwọ ni o gbẹyin kuro ninu yará. Ọkàn rẹ daamu pupọpupọ; inu rẹ bajẹ, ṣugbọn o mọ pe ọkàn rẹ mọ niwaju Ọlọrun: o ko mu apo owo naa.

O gbadura o si ni ki Ọlọrun ran ọ lọwọ lati le mu suuru ki o le "Kà gbogbo rẹ̀ si ayọ", titi Ọlọrun yoo fi fi otitọ hàn. Iwọ ni agbara lati gbẹkẹle Ọlọrun, gẹgẹ bi ọdọmọkunrin Dafidi nigba ti o jade lati ba Goliati omiran ja, nitori o wi pe: "Oluwa ti o gbà mi lọwọ́ kiniun ati lọwọ́ amọtẹkun, on na ni yio gbà mi lọwọ́ Filistini yi" (1 Samueli 17:37). O ni irú igbẹkẹle ati igbagbọ́ kan naa ninu Ọlọrun nitori o ti ràn ọ lọwọ lati bori awọn idanwo miran, o si mọ pe Ọlọrun yoo ran ọ lọwọ ninu eleyi naa pẹlu. Ṣugbọn nigba ti wọn ba mọ ole naa, wo bi ayọ̀ rẹ yoo ti pọ to pe iwọ ti fi ara balẹ nigba iyiiriwo naa.

**Ọgbọ́n ti a ko le ṣe alaini**

Bibeli sọ siwaju si i nigbakigba ti o ba woye pe o ko ni ọgbọn to bi o ti yẹ, o ni lati "bère lọwọ Ọlọrun, ẹniti ifi fun gbogbo enia li ọ̀pọlọpọ, ti ki isi iba-ni-wi; a o si fifun u". Ṣugbọn nigba ti a ba n tọrọ ohunkohun lọwọ Ọlọrun igbagbọ́ wa ni lati duro ṣinṣin bi a ba n fẹ ki Ọlọrun dahun adura wa. Bi o ba jẹ pe ni iṣẹju kan a ro pe a n fẹ ki Ọlọrun tọ̀ wá wá ṣugbọn ni iṣẹju keji a n fẹ rin ọna ara wa, Ọlọrun ki i dahun iru adura ti n ṣiyemeji bẹẹ. Ri i pe o beere ni igbagbọ́, iru igbagbọ ati ifọkantan kan naa ti o ni nigba ti o ni ki Ọlọrun gbà ọ́ là, Ọlọrun yoo si dahun.

**Ifayaran**

"Ibukún ni fun ọkunrin ti o fi ọkàn rán idanwò". Nigba ti eniyan ba fayaran, tabi fi ara da idanwo tabi iyiiriwo lai tapa si ẹni naa tabi ohun naa ti n pa a lara, alabukún-fun ni. Ẹni ibukun Ọlọrun ni. Bi o ba si tẹra mọ lati fi suuru fara dà, ni ọjọ kan oun yoo gba "ade iye, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ"

Dajudaju, a mọ̀ pe Ọlọrun kò jẹ́ fi buburu dán ni wò. Ṣugbọn awọn eniyan a maa ri idanwo nigba ti a ba tipa ifẹkufẹ ara wọn, tabi iwarapapa ọkàn wọn, fa wọn lọ. Igba pupọ ni wọn maa n gba ifẹ lile ọkàn wọn laaye lati ti wọn sinu ẹ̀ṣẹ. Ṣugbọn Ọlọrun a maa tọ ni si ọna titọ. Iwọ ha n digba ro o boya Ọlọrun ni n tọ́ ọ ninu ohun ti iwọ n ṣe, tabi ifẹ inu rẹ ni o tọ́ ọ? Iwọ le mọ iyatọ. Ọlọrun yoo tọ́ ọ soke, ṣugbọn ifẹ inu rẹ le tọ́ ọ si isalẹ. Bi ara rẹ leere, "Eyi yoo ha ran mi lọwọ nipa ti ẹmi? Yoo ha jẹ́ fun anfaani mi ati fun ogo Ọlọrun? Bi o ba jẹ́ fun ogo Ọlọrun, nn o ṣe e". Ṣugbọn bi ero tabi ete kan ba wa ti o yà kuro lọna Ọlọrun, sá kọ̀ jalẹjalẹ.

Ọlọrun n fẹ lati tọ́ awọn eniyan Rẹ̀ ninu ohun keekeekee, ninu ohun gbogbo ti a n ṣe. Bi a ba gbà fun un, Oun yoo tọ́ wa yoo si lò wa ninu iṣẹ Ihinrere, nitori Oun ni i ṣe Olufunni ni gbogbo ẹbun rere ati gbogbo ẹbun pipe.

**O le Gbala, O si le Pamọ**

Awa ti i ṣe Onigbagbọ́, a ti tun wa bí nipa Ọrọ Ọlọrun ati Ẹmi Rẹ̀, ninu ẹkọ wa ti oni ni a si ni awọn itọni, eyi ti, bi a ba tẹle, yoo ṣe wa ni Onigbagbọ́ ododo titi ayeraye. "Jẹ ki olukuluku enia ki o mã yara lati gbọ́, ki o lọra lati fọhùn, ki o lọra lati binu". Mura tán pẹlu itara lati gbọ́ ohun ti Ọlọrun

wi, ṣugbọn má ṣe yara lati ṣọrọ, lati fi aàye silẹ lati ru ibinu tabi ikannu rẹ soke. Kuro ninu ẹ̀ṣẹ gbogbo, si yẹ̀ wọn sapa kan -- ẹṣẹ nla ati keekeekee – ka Bibeli ki o si gba a rò, ki o si gbọran si i, nitori Ọrọ Ọlọrun lagbara lati gba ọkàn rẹ là ati lati pa ọ mọ́ titi iwọ yoo fi wọ Ọrun.

### Anfaani Igbagbọ́

Peteru Apọsteli n sọ nipa ayọ̀ Onigbagbọ ninu igbala ati ifẹ rẹ̀ fun Kristi Jesu bi o ti lẹ jẹ́ pe nigba miiran ọkan rẹ a maa wuwo nitori idanwo ati iyiiriwo ti n de lati dán igbagbọ́ rẹ̀ wo -- igbagbọ́ ti o ni nigba ti o kọ́ tọ́ Ọlọrun wa, igbagbọ pe Ọlọrun yoo gba oun yoo si pa oun mọ ni oloootọ ni ọjọ ayé oun gbogbo.

Igbagbọ yii niye lori pupọ, o ṣọwọn pupọ, nitori yoo mú ki Onigbagbọ le jolootọ titi Jesu yoo fi de lati mu un lọ lati maa gbé ni Ọrun lae ati laelae. Nitori naa bẹẹ gẹgẹ ni Ọlọrun n dán wa wò, O si n yọ igbagbọ́ wa nipa idanwo bi ina ti a n ba pade, gẹgẹ bi a ti fi igbona-gbooru ina ileeru da wura ti a wà ninu ilẹ titi yoo fi dabi digi.

### Fun Eredi kan

A ko gbọdọ ka a si ohun ajeji, bi ohun ti ko yẹ lati ri bẹẹ, a ko gbọdọ bẹru, ṣugbọn a ni lati ranti pe Oluwa n ṣe eyi lati le dán wa wò ati lati yiiri wa wò. A ni lati yọ̀ ki inu wa si maa dùn pé a ni ipin ninu iru iya kan naa eyi ti Jesu là kọja. Jesu mọ iru inira ti a n ni nigba ti idanwo ba de. A ti dan An wò ni gbogbo ọna ti a fi n dan awa naa wò, O si le ran wa lọwọ. (Heberu 2:18; 4:15).

Bi awọn eniyan ba sọrọ iwọsi, ọrọ ti n gun ni si wa nitori a jẹ́ Onigbagbọ́, o yẹ ki a yọ̀. Ohun ti o le a maa dé nigba miiran olukuluku eniyan ninu aye. Ani awọn agabagebe ati ẹlẹṣẹ paapaa ni inira ti o le lati fara dà, ṣugbọn Bibeli sọ fun wa pe ki a má ṣe jiya bi ẹlẹṣẹ. Awọn apaniyan, ole ati awọn ti n toju bọ ọrọ ọlọrọ paapaa a maa jiya nitori iṣẹ wọn. Ṣugbọn bi a ba n sọrọ wa ni ibi ti a si n fi wa ṣe ẹlẹya nitori a ko lọ si ile faaji, nitori a kò jó, nitori a ko kun ete ki a si ṣe bi awọn eniyan ayé ti n ṣe, eyi ko gbọdọ ti wa loju.

Nigba miiran awọn eniyan a fẹ lati doju ti wa nitori a n huwa ti a si n gbe igbesi-aye Onigbagbọ, ṣugbọn lori wọn ni itiju wa nitori wọn n gbé bi ẹlẹṣẹ.

### Ẹlẹda wa Oloootọ

Gẹgẹ bi Onigbagbọ a mọ̀ pe a ni lati jẹ oloootọ si Ọlọrun lojoojumọ ki a ba le wa ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba dé. Nigba naa ki ni yoo jẹ́ opin awọn alaibikita, awọn ti ko lakaka lati ṣẹ ifẹ Ọlọrun? Idajọ Ọlọrun nikan ni wọn le maa wo ọna fun. Ṣugbọn ẹ jẹ ki a maa yọ̀ ninu ijiya ti o dé lati fi ifẹ wa si I hàn ati lati dán igbagbọ wa ninu Ọlọrun wò, Ẹlẹda Olootọ, Ẹni ti n ṣẹṣọọ lori wa ki yoo fi àye silẹ fun idanwo to o lagbara ju wa lọ ki o de ba wa (1 Kọrinti 10:13).

### AWỌN IBEERE

1. Lati inu iwe wo ni a ti kọ́ awọn ẹkọ ti o niye lori bayii?
2. Ki ni idanwo?
3. Ki ni itọni kin-in-ni ninu ẹkọ oni?
4. Ki ni idanwo ati iyiiriwo n ṣe fun Onigbagbọ́?
5. Iru adura wo ni Ọlọrun n dahun?
6. Ki ni eniyan yoo ri gbà bi o ba fi ayọ̀ fi aya rán idanwo?
7. Ki ni n jẹ ki a fi ibi dán eniyan wò?
8. Ki ni ohun naa ti o niye lori tabi ti o ṣọwọn ju wura lọ?
9. Ki ni ṣe ti a ko gbọdọ tiju bi a ba jiya nitori a jẹ́ Onigbagbọ?